**ADURA NEHEMIAH FUN AWỌN ENIYAN RẸ̀**

**Nehemiah 1:1-11; 2:1-8; 9:1-38.**

**ẸKỌ 445 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ati ohunkohun ti awa ba bère, awa nri gbà lọdọ rẹ̀, nitoriti awa npa ofin rẹ̀ mọ́, awa si nṣe nkan wọnni ti o dara loju rẹ̀" (1 Johannu 3:22).**

**Ihin Ibanujẹ́**

Ni ọna jijin si ilu ibilẹ rẹ̀, ni ilẹ ajeji, ni ọmọ Israẹli kan ti a n pè ni Nehemiah n gbé. Ipo nla ni a fi i si ni aafin ọba ni Ṣuṣani. Nibẹ ni a fun un ni anfaani lati maa ṣe iranṣẹ fun ọba ṣugbọn inu rẹ̀ kò dùn pupọ. Kò dẹkun lati maa ronu nipa ilẹ ti o ti jẹ́ ibugbe awọn eniyan rẹ̀, ati Jerusalẹmu nibi ti a kọ́ Tẹmpili si, ninu eyi ti awọn Ọmọ Israẹli ti maa n jọsin.

Ni ọjọ kan o pade awọn ọkunrin Juda kan ti wọn wá lati ilu ibilẹ rẹ̀. O n fẹ́ gbọ́ iroyin nipa Jerusalẹmu. Nehemiah bi wọn nipa awọn eniyan ati Tẹmpili ti o wà nibẹ. Ṣugbọn iroyin ti o daya fo ni, ti o si ba ni lọkan jẹ́ ni awọn ọkunrin naa fun un. Wọn ni awọn eniyan naa "mbẹ ninu wahala nla ati ẹ̀gan". A sọ fun un pe a ti wó odi ilu naa lulẹ, a si fi ilẹkun rẹ̀ jona. Ni igba atijọ a maa n fi odi yí awọn ilu ká fun aabo. Nipa awọn ilẹkun odi, ti a n tì loru nikan ni awọn eniyan naa le bá wọle, ti wọn si le bá jade ni ilu. Nehemiah mọ̀ pe ilu Jerusalẹmu ati Tẹmpili naa nibi ti awọn eniyan Ọlọrun n jọsin kò ni aabo ti wọn ni lati ní. Ọkàn Nehemiah bajẹ to bẹẹ ti o fi sọkún.

**Adura**

Nehemiah kò fi ọran naa mọ ni sisọkun ati ni ṣiṣọfọ nikan. O gbaawẹ o si gbadura. Dajudaju o mọ̀ nipa adura Sọlomọni nigba ti a kọ́ Tẹmpili akọkọ. Sọlomọni ti bẹ Ọlọrun pe ki O gbọ́ ki o si dahun adura awọn igbekun ti yoo gbadura si Ọlọrun "siha ilu yi …… ati ile" ti o ti kọ́ fun orukọ Oluwa (2 Kronika 6:34, 35). Ọlọrun gba ẹbọ ati adura Sọlomọni, O si dahun ẹ̀bẹ awọn igbekun naa.

**Daniẹli**

A ti kà pe Daniẹli gbadura pẹlu ferese rẹ̀ ni ṣiṣi silẹ si iha Jerusalẹmu. Nigba mẹta lojumọ ni o kunlẹ ti o si n gbadura; o fi ọpẹ fun Ọlọrun rẹ̀ (Daniẹli 6:10). A tun ti kà á pe Ọlọrun dahun adura Daniẹli nigba ti a sọ ọ si inu iho kiniun. Ọba kigbe pe, "Daniẹli! iranṣẹ Ọlọrun alãye! Ọlọrun rẹ, ẹniti iwọ nsin laisimi, ha le gbà ọ lọwọ awọn kiniun bi?" (Daniẹli 6:20). A ranti pe Ọlọrun "di awọn kiniun na lẹnu" kò si si ipalara kankan ti o dé bá Daniẹli "nitoriti o gbà Ọlọrun rẹ̀ gbọ́".

**Apẹẹrẹ Rere**

Awọn eniyan Ọlọrun wọnyii fi apẹẹrẹ lelẹ fun wa lonii -- lati maa gbadura. Ninu Luku 18:1, a ka pe Jesu pa owe kan nitori eyi yii pe "o yẹ ki a mã gbadura nigbagbogbo, ki a má si ṣãrẹ̀". Ni ẹsẹ Iwe Mimọ́ miiran, Jesu n rán wa leti lati maa ṣọ́nà ki a si maa gbadura. Ninu iwe rẹ̀ si awọn ara Filippi, Paulu pẹlu nipa imisi Ọlọrun wi pe, "Ninu ohun gbogbo, nipa adura ati ẹbẹ pẹlu idupẹ, ẹ mã fi ibere nyin hàn fun Ọlọrun" (Filippi 4:6). Nigba ti Paulu n darukọ "gbogbo ihamọra Ọlọrun", o tẹnumọ ọn pe, pẹlu awọn ihamọra wọnyii, awọn ọmọ-ogun Ọlọrun ni lati maa gbadura nigba gbogbo (Efesu 6:13-18).

**Adura Gbà**

Nehemiah mọ̀ pe adura kọja ọrọ lasan. O mọ̀ pe bi eniyan ba n fẹ idahun si adura rẹ̀, o ni awọn ohun ti o ni lati ṣe. Nehemiah rán Ọlọrun leti pe Ọlọrun oloootọ ni Oun si awọn ti "o fẹ ẹ, ti nwọn si pa ofin rẹ̀ mọ". Jesu fi iru ọrọ yii kọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. Jesu wi pe, "Bi ẹnyin ba fẹran mi, ẹ ó pa ofin mi mọ́" (Johannu 14:15). Ninu Jakọbu 1:22 a ka pe, "ṣugbọn ki ẹ jẹ oluṣe ọ̀rọ na, ki o má si ṣe

olugbọ́ nikan”. Nehemiah kò ni ṣai ti fẹran Oluwa ki o si pa ofin Rẹ̀ mọ́, bi bẹẹ kọ́ oun ki ba ti mu un wá si iranti Ọlọrun.

Bi o ti n gbadura, Nehemiah kò dá ara rẹ̀ lare, kò si sọ fun Ọlọrun bi oun ti jẹ́ eniyan rere tó. O gbà pe oun ti n dẹṣẹ tẹlẹtẹlẹ, ṣugbọn o rọ̀ mọ́ ileri Ọlọrun fun idariji. Nehemiah rán Ọlọrun leti Ọrọ Rẹ̀ lati ẹnu Mose: “ Yipada si OLUWA Ọlọrun rẹ, …. si gbà ohùn rẹ̀ gbọ́,… pẹlu àiya rẹ gbogbo, ati pẹlu ọkàn rẹ gbogbo: nigbana ni OLUWA Ọlọrun rẹ yio …. si ṣãnu fun ọ” (Deuteronomi 30:1-3). Nehemiah jẹwọ pe a ti tú awọn ọmọ Israẹli ká nitori ti wọn kò pa ilana Ọlọrun mọ́ gẹgẹ bi Ọlọrun ti wi. Ṣugbọn Nehemiah ti yipada si Ọlọrun, o ti pa ilana Rẹ̀ mọ́, o si n reti pe Ọlọrun yoo ràn oun lọwọ lati pada si Jerusalẹmu, “si ibi ti” Ọlọrun “ti yàn” lati fi orukọ Rẹ̀ si.

### Idahun

Bawo ni Ọlọrun ṣe dahun adura Nehemiah? Lẹyin oṣu mẹrin, Nehemiah, pẹlu oju fifaro, n ṣe iranṣẹ fun ọba. Oju rẹ̀ ko ti i faro bẹẹ niwaju ọba ri. Ọba beere eredi rẹ̀ ti inu rẹ̀ fi bajẹ. Ọba wi pe o ni lati jẹ́ “ibanujẹ ọkàn” niwọn bi Nehemiah kò ṣaisàn. Bi ẹ̀ru tilẹ n ba Nehemiah, o ni lati dá ọba lohun, nitori naa o royin fun un nipa ipo ibanujẹ ti Jerusalẹmu ilu ibilẹ rẹ̀ wa. Ọba beere ohun ti o fẹ ṣe. Nehemiah tọrọ àaye lati pada si Jerusalẹmu lati le tún odi naa mọ.

### Ipinnu

Nehemiah kò gbadura ki o si gba Ọlọrun gbọ́ nikan, ṣugbọn o fẹ lati ṣe ojuṣe ti rẹ̀ ki iru ipo ti Jerusalẹmu wa le yipada si rere. Awọn ẹlomiran a maa gbadura ṣugbọn wọn ko fẹ ṣe ohunkohun lati ṣe iranwọ. Iwe Jakọbu sọ nipa ẹni ti o ri arakunrin tabi arabinrin kan ti o ṣe alaini ti o si wi pe, “Ẹ mã lọ li alafia, ki ara nyin ki o maṣe tutu, ki ẹ si yó” (Jakọbu 2:16); ṣugbọn ko fi nnkan wọnni ti ara n fẹ́ fun wọn. Ere ki ni o jẹ́? Nigba ti o wà nipa wa lati ṣe iranlọwọ, adura nikan kò tó.

Nehemiah mura tán lati fi aafin ọba ti o tu ni lara silẹ lọ ṣiṣẹ fun Oluwa. Nehemiah tọrọ àaye lati lọ si Jerusalẹmu a si fi fun un. Ju bẹẹ lọ, ọba fun un ni awọn eniyan ati ẹṣin lati sin in lọ, ati iwe ẹri rere. Ninu Iwe Oniwasu 9:10 a ka a pe, “Ohunkohun ti ọwọ rẹ ri ni ṣiṣe, fi agbara rẹ ṣe e”. Bẹẹ gẹgẹ ni Nehemiah ṣe. Iwe ẹri ti o mú lọwọ fun un ni ẹtọ si igi lati inu igbo ọba, eyi fi han ni pe o ti mura tán lati kọle. Ẹkọ wa ti n bọ̀ fi ye ni pe Nehemiah pada si Jerusalẹmu, a si mọ odi naa.

### Ọrọ Ọlọrun

Bi ẹ̀dùn kikọ ile ti wà lọkan Nehemiah, bẹẹ ni o ni ẹ̀dùn awọn eniyan rẹ̀ lọkan pẹlu. O mọ pe bi wọn o ba gba ibukun Ọlọrun wọn ni lati gbọran si Ọrọ Ọlọrun. Ki wọn to le gbọran, wọn ni lati mọ ohun ti Ọrọ Ọlọrun wi. Lai pẹ jọjọ lẹyin ti a pari odi kikọ́, Nehemiah jẹ baalẹ (Nehemiah 8:9). A rọ awọn eniyan naa lati kó ara wọn jọ lati gbọ́ “iwe ofin Mose ti OLUWA ti paṣẹ fun Israẹli”. Awọn eniyan naa kò jẹ́ olugbọ nikan, ṣugbọn wọn bẹrẹ si gbọran si Ọrọ Ọlọrun.

Ẹsra akọwe ṣi iwe o si kọ́ awọn eniyan. Wọn ri pe a ti kọ́ pe wọn ni lati pa Ase Agọ mọ́. Wọn mu ẹka igi wọn si fi pa agọ ninu eyi ti wọn gbé laaarin ọsẹ agọ naa gẹgẹ bi Ofin ti palaṣẹ. Lojoojumọ wọn ka iwe Ofin, eyi ti i ṣe apa kin-in-ni Bibeli. Wo bi inu wọn ti dun to nitori ti wọn gbọran si Ọlọrun lẹnu! Lati igba Joṣua, ti o kó awọn Ọmọ Israẹli wọ Ilẹ Ileri, ni wọn ti ṣai naani pipa Ase Agọ mọ́. Wo iru ayọ̀ ti o gba ọkàn wọn kan nigba ti wọn gbọran! Bẹẹ ni lọjọ oni; a maa n ni ayọ̀ tootọ nipa gbigbọran si Bibeli, Ọrọ Ọlọrun.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni iṣẹ Nehemiah ni Ṣuṣani, aafin?
2. Bawo ni o ṣe gbọ́ nipa ipò ti Jerusalẹmu wà?
3. Njẹ inu rẹ̀ dùn nigba ti o gbọ́?
4. Ki ni ṣe ti Nehemiah fi gbadura?
5. Ki ni o tun ṣe, yatọ si gbigbadura?

6. Bawo ni ọba ṣe ran Nehemiah lọwọ?
7. Ki ni ṣe ti Nehemiah fi lọ si Jerusalẹmu?
8. Bawo ni Ọlọrun ṣe dahun adura Nehemiah?
9. Bawo ni Nehemiah ṣe ran awọn eniyan rẹ̀ lọwọ?
10. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe nigba ti wọn gbọ́ Ọrọ Ọlọrun?